Iwẹ ọjọ Jimoh jẹ dandan lori gbogbo ẹni ti o ti balaga, ki o si fi pako run awọn eyin rẹ, ki o si lo lọ́fínńdà ti o ba ri

Lati ọdọ Amru ọmọ Sulaym Al-Ansari, o sọ pe: Mo n jẹ́rìí sí Abu Saheed pe o sọ pe: Mo n jẹrii si ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a - o sọ pe: «Iwẹ ọjọ Jimoh jẹ dandan lori gbogbo ẹni ti o ti balaga, ki o si fi pako run awọn eyin rẹ, ki o si lo lọ́fínńdà ti o ba ri».
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe alaye pe dajudaju iwẹ ọjọ Jimoh kanpa o da gẹgẹ bii ọranyan fun gbogbo ọkunrin ti o ti balaga ninu awọn musulumi ninu awọn ti Jimoh jẹ dandan fun. Ati pe ki o mọ awọn eyin rẹ pẹlu pákò ati nkan ti o jọ ọ. Ati ki o lo lọ́fínńdà pẹlu èyíkéyìí oorun aladidun.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/10036

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee